o kọ kuro nibi ẹjẹ jiję, o wa sọ pe: “Dajudaju ẹjẹ jiję o ki n mu oore wa, bi ko ṣe pe wọn maa n fi gba nnkan jade lati ọwọ ahun ni”

Lati ọdọ ọmọ Umar ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji: Lati ọdọ Anabi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- dajudaju o kọ kuro nibi ẹjẹ jiję, o wa sọ pe: “Dajudaju ẹjẹ jiję o ki n mu oore wa, bi ko ṣe pe wọn maa n fi gba nnkan jade lati ọwọ ahun ni”.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- kọ kuro nibi ileri, oun ni ki eniyan ṣe nnkan kan ni dandan fun ara rẹ ti Ọba aṣofin ko ṣe ni dandan fun un, o sọ pe: Nitori pe ileri ko ti nnkan ṣíwájú ko si lọ ọ lara, bi ko ṣe pe wọn maa n mu u jade lati ọdọ ahun ti ko ki n ṣe nnkan kan afi nnkan ti o jẹ dandan le e lori, ati pe dajudaju ileri ko ki n mu nnkan kan wa ti wọn ko tii kadara rẹ fun un.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/2960